# AZIKIWE FE BINU F'ISE ISELU SILE





*AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hihu-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*



# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



*TO CLEAR*

*Gents Suede Court Shoe Brown, Black & Grey Before 50/- Now 42/6*

Obtainable at :-

A. B. AKINYEMI

*10A Moloney Bridge*

LAGOS.



VOL. No. VIII 477. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JULY 21, 1956 KỌBỌ MEJI (2d.




Aworan ti a nwo yi ni ti Ọlọla Amanze Njoku ti o nṣe alabojuto iṣẹ owo ati iṣẹ ọwọ nilẹ Nigeria.

On ni Alabojuto ile owo ni ilu Norway tọkasi fun awọn Oniwe Irohin ilẹ Nigeria wipe o ti kọkọ ṣiwaju wa silu Norway nipasẹ ọrọ ẹja Panla tabi Abọmafọ.

Ọlọla Amanze Njoku yi ni Alakoso iwe irohin wa yi mẹnu kan ninu ọrọ irin ajo rẹ lọ silu Norway lọsẹ to kọja on ni ẹniti o sọrọ fun wọn nigbana ti nwọn fi din Ṣile mẹdọgbọn kuro lori iye owo ẹja Panla.

Ọlọla Amanze Njoku jẹ ọkan ninu awọn aṣiwaju ninu iṣẹ ṣelu nilẹ Ibo, o si tun jẹ ọkan ninu awọn Minister fun iṣẹ ọwọ ati iṣẹ Owo ṣiṣẹ (Commerce and Industries) fun Ilu Eko (Federal Goverment)

## Owe Yoruba

Owu Aguala ko mọlẹ to Oṣupa Ọlọrun ni ko fifun. Bi Ọlọrun ba da Kanyin-Kanyin ko tobi bi ẹṣin, atapa ni iba ta enia.


THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati Ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbalye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Eja Panla ko ni Ori Enia



Aworan inu iwe wa yi niti Alakoso Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ yi ti o gbe ẹja Panla tutu dani ti o fi nhan gbogbo enyin ọkawe wa ri s'oju lati le fi mọ amọdaju gbamgba wipe ẹja Panla ko ni ori bi ti enia, ori ẹja ni ori rẹ.

Eyeke 'ṣe, eke ni pani.

## Azikiwe Fe Binu F'ise Iselu Sile

ENUGU. Irohin kan wa wipe Dokita Azikiwe ti o nṣe Alakoso Ijọba Ila-Orun (Eastern Nigeria Prime Minister) ṣeleri wipe laarin ọjọ meta, on yio fi iṣẹ iṣelu silẹ.

Nitori ọrọ yi, awọn igbimọ (House of Assembly) ti apa Ila Orun, ti pe ipade pataki kan lati gbọ idi ọrọ pataki lọnu Ogbeni Azikiwe nipa fifi iṣẹ iṣelu na silẹ.

(Wo yo ku loju ewe kejọ)

## Awon Omo Ilewe Towo Lo Ri Ijoba

EKO. O ti jẹ aṣa fun awọn Olotu moto Akero lati ma ko fun kiko awọn ọmọ ilewe si inu moto wọn.

Eyi ni awọn igbimọ Lagos Town Council ti ti awọn ṣe ti ikilọ yi sode.

Opolopo ni awọn olotu ọkọ ero ti awọn ma nkọ lati ko awọn ọmọ ilewe sinu moto wọn nitori ti owo wọn kere-kọrọkọrọ lati Yaba titi de Eko.

Nigba pupọ ni awọn ọmọ ilewe ma npada wa sile nigbati awọn ko ri moto wọ. Nigba miran awọn olotu nmọyi a ma da awọn ọmọ ilewe pada sihiti awọn ti gbe wọn lọ nitorine, awọn ko le gba kọbọ ti ọmọ ilewe na fun wọn.

L'ọsẹ to kọja lọ yi, awọn ọmọ ilewe ti iwọn ọgọrun enia lo lọwọ lọ sọdọ awọn olotu Lagos Town Council lati fi ẹjọ awọn olotu ọkọ akero sun pe nipa iwa buruku ti awọn nhu si wọn. Ẹnyin Conductor (olotu) ọkọ ero ẹsọ di ọwọ nyin o, Ẹniti ko ba tẹle ikilọ yi, ijọba yio gba iwe aṣẹ rẹ ko ni le ṣiṣẹ moto ak'ero mọ.

## Sardauna ko Ranse P'eni-kan

Irohin ti gbojikan kakiri Oke Ọya wipe Sardauna ti o nṣe Prime Minister ilẹ Hausa ti ranṣe si Colonel Nassar to nṣe Prime Minister fun ilẹ Egypt wipe ki o wa si ilẹ awọn Hausa nilẹ Nigeria lati wa ṣe ayẹwo nitoripe gẹgẹbi awọn ti ṣe Musulumi, awọn nfẹ pamọ pẹlu ilẹ Musulumi.

Irohin de lati ilẹ Egypt pe ọrọ ko jẹbẹ rara; nitotọ ni Sardauna Ṣokoto ya ki Colonel Nassar ni Egypt nigbati o nkoja lọ si Mẹka, ṣugbọn awọn mejeji yi ko fi ẹnu kan iru ọrọ to jọbẹ.

Eniti o da ọrọ yi silẹ ni Colonel Anwar Elsadat tisko ti eleyini wa bẹ ilẹ Nigeria wo, on lo sọrọ Sardauna Ṣokoto fun Colonel Narssar baba ẹgbẹ ilẹ Egypt. On lo mu ki Nassar ranṣẹ pe Sardauna ki o wa bẹ Egypt wo, on Elsadat kanna lo tun wipe ki Nassar wa bẹ ilẹ Hausa wo. Nitorina ko nṣe Sardauna lo pe Nassar pe ki o wa si ilẹ Hausa.

## Owe Yoruba

**Ibiti o wu efufu lele ni ndarigbe si, ibiti o wu olowo eni lo nran ni lo.**


**Now Available**

BUGLES, BEDSTEADS,
PAINTS, DISTEMPERS
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
and NEW COURT ROAD.
IBADAN





# Itan Egba Niba Soki

Awọn Arọkin sọ wipe, awọn Egba ni iran ti o pọjulọ ninu iran Yoruba awọn ni pataki ti o nkọ ila Pele mẹta, iran Yoruba ni ko nkọ ila rara. Awọn ọmọba tabi ọmọ Oduduwa l'o nkọ ila abaja.

Ninu awọn Balogun to ba Oduduwa de sile Ifẹ ni Olugbọn, kẹkẹ ni ila ti o mbẹ l'oju rẹ. Ekiti tun jẹ ọkan ninu awọn Balogun rẹ. Idoko ni ila tirẹ.

Lasiko ti ko si ogun larin awọn Ẹgba, ara rọ wọn, ko si ọtẹ l'arin wọn, ni ilu Ketu ni nwọn fi ṣe ibugbe. Laifa ọrọ gun, ogun Idahọmi bẹlu wọn, nwọn si ṣe ọkunrin l'oju ija. Ṣugbọn nigbati ogun pari tan, ọtẹ tẹ wọn tobẹ ti nwọn ni lati bẹrẹ si fọn kakiri.

Ọpọlọpọ wọn, lẹhin iriri pupọ, nwọn tẹdo si ibiti a npe ni Abeokuta l'oni, Omiran tẹdo si Ijaye, Ogbomọṣọ, Ọyọ ati Ibadan.

Awọn ti o mulẹ pẹlu Olugbọn bẹrẹsi bimọ silẹ Ikoyi, Ijaiye ati Ogbomọṣọ. Awọn Ẹgba ati Ogbomọṣọ ati Ijaiye ati Ọyọ papọ di ara kan, awọn si nabe ara wọn nija bi ogun bade si ẹnikan, nitorina, awọn ọmọ ti nwọn bi silẹ Ọyọ, bi nwọn ba kọ pele Ẹgba si l'ọju tan, nwọn o tun fi abaja Ọyọ tẹle lẹgbẹ, lati fi han wipe Ọyọ ni a gbe bi wọn si, ṣugbọn iran Ẹgba ni nwọn. Iru awọn onila meje-meje bayi lo tẹ ilu Ibadan do gẹgẹbi Lagelu.

Awọn ti o mulẹ pẹlu Olugbọn, ti nwọn ti di ọkanna pẹlu Ọyọ, ama kọ ila pele lati fihan wipe iran Ẹgba ni wọn, nwọn jẹ ọmọ ibilẹ agbegbe Ọyọ eyi ni abaja mẹta ti nwọn tun fi pẹlu, nwọn si mbẹ l'abẹ Olugbọn, eyi ni kẹkẹ ti nwọn tun fi pẹlu Ere Ori Olugbọn ti o wọ kẹkẹ mbẹ ninu igbo Irumọlẹ titi di oni oloni.

Iran Yoruba ni Ifẹ ati Eko. Yoruba ko nkọ ila kọkan, ere ori rẹ mbẹ nile Ifẹ titi di oni. Ori Yoruba ni nwọn npe ni Olokun. Eko ni Olokun nbe fi ṣe ibujoko, Olofin Ile Ifẹ lo si npaṣẹ de ibe.

Enikẹta ni Balogun Ekiti, Idoko lo mbẹ l'oju re, nigbati o kuro ni Ifẹ o lo tẹdo si Ọwọ.


## AKIYESI PATAKI

**Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,**

LỌ SI:-

**18, Race Course Road,**

OKE—PADI, IBADAN.

**E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun okan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—Ofe nigba gbogbo.**

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa Lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

## ABOKI



JẸ AWOGBARUN to Lokiki ka ILẸ ENIA DUDU.

AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JẸDIJẸDI, ETC.

KOṢEFẸKU ni Gbogbonse yi je fun GBOGBO ILE nitorina RA IGO kan loni. Lọdọ:-

**IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,**

Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN,

E 21, SABONGERI, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205, Kumasi, Gold Coast.

## Awon Dokita Fi Han Wipe

**Ose Palmolive Le Jeki Ara Re Dan Ki o jolo Larin ojo Merinla**



**Ara Mi Dan, O Si jolo Nitoripe Mo Tele Ilana Ti Awon Dokita Se**




EPO ILE AFIRIKA NI A FI ṢE ỌṢẸ YI

COLGATE PALMOLIVE LO'ṢB

# E L E T I   Q F E

A-NJU-WỌN KO SI WI L'FJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kesoko Street, Lagos "ELETI-QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 477, LAGOS, SATURDAY JULY. 21, 1956.


## Ile we Ofe Nilu Eko

L'ori ise ofin ti a şe ninu oşu March. 1955. Ijọba yio pese Ilewe-Qfẹ fun awọn ọmọde elakọbẹrẹ nile Eko, lẹbiti ọjọ kini oşu January ti ọdun 1957, ti o mbọ.

A fi wasika a nse i ş alaye fun ẹnyin enia wa gẹgẹ i nwọn ti ş ti ifi r kọ awọn ọmọ silẹ fun ilewe-Qfẹ na, o k fi ni si iyọnu fun ẹnikẹ i lati lọ fi oruko ọmọ rẹ silẹ.

Ekini: Gbogbo ọmọ ti o ba ti nlọ si ilewe ti Ijọba mọ, (Approved Voluntary Agency) yio jẹ anfani ilewe-Qfẹ, nitorina ko si wahala lati tun fi orukọ awọn ọmọ bẹ silẹ mọ.

Ekeji :- A o ileti fi oruko awọn ọmọ ti o bati to ọdun marun tabi ti koiti ju ọdun mefa lọ ni ọjọ kini oşu January, ọdun 1957, ti o mbọ yi. Awọn ti koiti bẹrẹ si lọ si ilewe ni o. Ni akotan, awọn ọmọ ti a ti bi nu ọdun 1951 l'o ti bẹrẹ.

Ẹkẹta :- Gẹgẹbi o ti jẹ wipe a ko gbọdọ ş'ai gba'we ọmọ ti a ba bi nilu Eko yi, eyi yio jẹ irọrun fun awọn obi, Iya tabi Baba tabi Alagbatọ ọmọ lati mu Iwe ọjọ ibi ọmọ dani lati jẹri si ọjọ ori ọmọ na, nigbati nwọn ba nlọ fi orukọ ọmọ wọn silẹ, ati pataki ni ki o daju wipe, iya tabi baba tabi Alagbatọ ọmọ na ngbe ilu Eko.

Adọta aye ni nwọn yio şe fun fifi orukọ silẹ, awọn akọwe agba Orukọ silẹ merin-merin ni yio wa fun aye kọkan. Lati agogo mẹjọ owurọ di agogo mẹwa ati agogo mẹrin di mẹfa aşalẹ, ni ao fi ma fi orukọ silẹ l'ojojumọ fun ọjọ mẹrin; yio bẹrẹ l'ọjọ 25th, 26th, 27th ati 28th oşu yi.

Eyiti o jẹ pataki ni a se alaye rẹ s'oke fun enyin enia wa, awọn pẹpẹpẹ y'oku, awọn akọwe agba orukọ silẹ yio ma la ye yin. Nitorina, ki ẹ maşe jafara lati lọ fi orukọ awọn ọmọ yin silẹ fun ilewe-ọfẹ o.




Bi o ba nsise nile re fi Egbogi Ajebidan yi pa ibiti o ndun o

ELECTRIC Balm




## Afojudi Ha Ni Eyi Tabi Ekeji Re !

Lọjọ kan laipẹ yi, nilẹ Yoruba, Adajọ kan wa lori atẹ idajọ ninu ile ẹgbẹ ilu na, bẹni ọkan ninu awọn Lọya ti o si jẹ ọkan pataki ninu awọn Oşelu, wọ'le tọ Adajọ lọ, o si wipe.

Alagba! ki ẹ pẹ, ẹnyin ni a nduro de ki ẹ tete şe giri, ki ẹ jade, nitori a ti sanwo lati lo ile ẹgbẹ yi fun ajọsọ ọrọ larin ẹgbẹ wa.

Adajọ na dahun pe, aha! kinla, iwọ lọya yi ma ni afojudi o, bi ko to iberu ko ba to isaju ẹdan? Njẹ bi alaimọkan ba şe iru eyi, iwọ ko ha ni mọ ọrọ ti o ni lati sọ? Imi ẹran nidi enia wo ni yi?

Afaru, ki nfẹ o. ku, afojudi ni, tabi ekeji rẹ ha, ha, O ma koku laiya o, iwọ ri awọn oyinbo, awọn Ọlọpa, ati awọn ijoye, olukuluku duro, nwọn si tẹriba, ko nşe emi ni nwọn mbọwọ fun bikoşe Ọba.

Bẹni lọya na ba fi itiju jade kuro ni kotu.

## Oro Alafin Ko Se Alafin Fe Da Ija Sile

ỌYỌ Irohin gbọ kan kakiri ilẹ Ọyọ nigbati Iyafin Koşemani fi ko awọn obinrin sodi ti nwọn si ranşẹ si Ajẹlẹ Ọyọ wipe ki o wa pade wọn ni Ọja Akẹsan. Nigbati o lọ pade wọn, nwọn sọ fun pe ijọngbọn yio bẹ silẹ bi nwọn ko ba mu Alafin titun ti nwọn jẹ kuro. Ajẹlẹ si wi fun wọn wipe tani sọ fun wọn pe nwọn ti jẹ Alafin miran.

Ajẹlẹ tun fi ye wọn wipe, bi Gomina ko baiti fi aşẹ si, a ko gbọdọ jẹ Alafin miran, titi ti awọn Ọyọmisi ma fi mu ẹniti nwọn yan lọ han Gomina ti Gomina yio fi aşẹ si.

Ni gẹrẹ ti awọn obinrin tuka lọ tan ni awọn okunrin kan tun tọwọ de, nwọn ni ọmọba ni awọn, Nwọn wi fun Ajẹle wipe, awọn ti o jẹ Ọmọba yi nikan lo ni aşẹ lati yan ẹniti o tọ lati je oye Alafin ko nşe awọn Ọyọmisi. Ọgbẹni Adelọdun lo si ko awọn enia ti o pe ara wọn ni ọmọba na sodi.

Ajẹlẹ na dahun pe, on gbọ gbogbo ohun ti nwọn wi, şugbọn gẹgẹbi nwọn ti wa sọ fun on yi, ki nwọn lọ si Ibadan bẹ ki nwọn lọ roh'n fun Minister of Local Government. Şugbọn ki o to di wipe awọn Ọyọmisi yan Bello Gbadegẹsin ni Alafin, nwọn ti kọkọ wi fun on tẹlẹ.





"HIS MASTER'S VOICE"

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# Irin Ajo lọ silu Norway
## Lati owo TAJU THOMPSON (2)

Awọn ile Apejẹ (Hotels) to wa nilu Norway dara pupọ, işẹ wọn dara, onjẹ ibẹ ko ni afiwe.

AWỌN ILU TI A DE

Awọn ilu pataki-pataki ti a de ni OSLO ti işe olu-ilu Norway, Bodo, Tromso, Hamerfest, Vardo, Slvovear ati Bergen. Bi o tiṣjẹ wipe Oslo ni olu-ilu Norway, Bergen ni awọn enia pataki ti jade. Ẹniti o kọkọ jẹ oye Alakoso ijọba ti Norway, ara ilu Bergen ni, ti o si fi di asiko ti a wa yi, gbogbo awọn enia pataki ni Norway, ilu Bergen ni nwọn ti jade wa.

ILE EGBẸ AWO-YI'RUN

Koşe f'ẹnu sọ ni Gbọngan nla tabi ile Ẹgbẹ ti nwọn kọ silu OSLO Owo ti nwon fi kọ ile ẹgbẹ na jẹ nkan bi Ọgọrin Ọkẹ-Pọun (£1,600,000)

Ọjọ kẹtadinlogun oşu May, ni lọdọdun ni nwọn ya sọtọ fun ayajọ ọjọ ti nwọn gba ominira ilu wọn, bi o ti jẹ wipe ọjọ kẹtale-logun oşu May, ni a de ilu na, sibẹ-sibẹ a ba apẹrẹ ohun ẹsọ ti nwọn fi şe ayajọ ọjọ Ominira ti ọdun'ni. Ọjọ ayọ nla aini-gbagbe ni ọjọ na jẹ nilu Norway, papa fun awọn ọmọ ilewe ti o jẹ wipe ara ti o ba wu olukuluku wọn ni yio ma da, nipa ohun jijẹ, mimu, ijo ati orişirişi faaji.

Nigbati a lọ bẹ ọlọla Alabojuto işẹ owo ilu na wo, Ọlọla Arne Skang. Ọgbẹni na kun fun ọgbọn ati iakaye ọmọluwabi enia si ni işe Gẹgẹbi diẹ ninu wa ti ni iwe eto owo ilu wa Nigeria pẹlu ti ilu Norway lọwọ, a fi siwaju rẹ wipe iye oja ti Nigeria nra nilu Norway ga pupọ ju oja ti ilu wọn nra lọwọ wa lọ, eyi ko si tọ wa l'ọrun. Ọlọla na fi ye wa wipe ọpọlọpọ oja ni awọn nra lati ilẹ wa ti o jẹ wipe lati ile işẹ abojuto itaja ti ijọba wa (Marketing Board) ni awọn ti nra, ko si da on l'oju wipe iro awọn oja bẹ wa ninu iwe eto ti a fi han on yi.

Nigbati a pada de ilu London, a lọ şe ayẹwo lọdọ Ọgbẹni D.H. Rosser ti işẹ Aşoju işẹ owo ile Nigeria şugbọn ero tirẹ ko ba ti Alabojuto işẹ owo ilu Norway dọgba.

ẸJA PANLA TABI ABỌMAFỌ

Mooi lati kọkọ lọ akoto irọ ti nwọn npa nilu wa nibin fun enyin ọkawe mi, ki eto ma ba ọrọ mi lọ siwaju. Irọ patapata ni wipe ẹja Panla ni ori ti o dabi ori enia, eyi ko jẹbẹ rara, ko si iyatọ kan lara ori ẹja Panla si ti awọn ẹja miran.

Bi o ti jẹ pe emi ko ni igbagbọ si irọ wọn na tẹlẹtẹlẹ, nigbati mo tun fi oju mi' ri, ko yẹ ki nma şe alaye rẹ fun yin; ohun ti o mu wọn ge ori ẹja Panla ni wipe ni ilẹ wọn l'ohun, ko si koriko lati fi şe onjẹ fun awọn ẹran gẹgẹbi ti ilẹ wa nibin, ori ẹja ni nwọn ifi şe onjẹ ẹran wọn eti papa julọ, awọn oyinbo ki i jẹ ori ẹja. Ẹja Panla ko ni ori ti o jọ ti enia rara o.

Lẹhinna, a tun m'ẹnu ba ti owo giga ti o wa l'ori ẹja Panla, awa Oniwe Irohin si fi han Alabojuto işẹ owo ilẹ Norway wipe Ijọba Nigeria ti mu owo Bode (Custom duty) kuro l'ori ẹja Panla, gẹgẹbi eredi ọrọ awọn oluta ẹja Panla ti nwọn lọ ri Ijọba wa, şugbọn awọn onişẹ Panla ti ilu Norway ko din owo Panla ku rara.

Ọlọla Alabojuto na sọ fun wa wipe ni asiko kan ninu ọdun tokọja, Ọlọla Amanze Njoku ti işe Alabojuto işẹ owo nilẹ Nigeria wa si Norway, o si sọ baxanna, nipa ọrọ rẹ, awọn din owo bi sile medọgbọn ku kuro l'ori iwọn ẹja Panla. Mo ro wipe eyi yio jẹ iyanu fun awọn onişowo Panla kekeke ti nwọn si ni igbagbọ wipe owo ẹja Panla koiti dinku. Gbogbo onişẹ ẹja Panla ti o wa nilu Norway l'o si mọ eyi nipa Ikede ti nwọn şe sinu awọn Iwe Irohin ilu na.

IWE IROHIN NILU NORWAY

Awọn Iwe Irohin mbẹ nilu Norway ti irisi wọn dara, eyi ti a npe ni Evening Post n iye iwe ti o ntẹ jade pọja, 150,000 ati ọkan ti a npe ni Evening Edition, 130,000 l'ojojumọ.

Bi o ti jẹ ohun ti o wọpọ nilu awọn Oyinbo, enia dudu funfun lati ma bere ọrọ iyanu l'owọ alejo, wọn ko şai bere wipe nibo ni enyin ti wa ?apa ibo ni ilu Nigeria wa l'abẹ Ọrun? awọn miran rope ilu

(Wo yoku loju ewe kejọ)



Aworan awọn Oniwe Irohin ti o lọ şe abẹwo ilu Onipanla (Norway) ni ẹ nwo ninu iwe wa yi. Ọgbẹni Layi Mabinuori, E. Effiong ati Taju Thompson, ni awọn Ọgbẹni Alex. Ola. Ori ati A. S. Badru ti a lọ pade wọn ni ibudo Ọkọ Ofurufu ni Ikeja. Alafia ni wọn de.

**Kere o!**

A ti n [illegible] rigirisi ogun Germany to sese d[illegible], fun omiruru [illegible] tokunri tobinrin. Tete wa [illegible] tire k'o to [illegible]

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7 Ererion Road, Lagos

**E ma ka iwe Irohin Eleti-Ofe ki e si ma polowo oja yin sinu re nigba gbogbo.**




**HÆMATOGEN**

O mbẹ ninu [illegible] fun tita kakiri Ṣọbu Nigeria [illegible] lọdọ Aṣoju wa:—

Alban Pharmacy Ltd. 2, Victoria Street,
P. O. BOX 461
Lagos—Nigeria.

## Aseju Baba Asete

Ọkunrin kan l'ọna ilẹ Oke, ti nwọn npe ni Sam Oloke-ilẹ, ni a ri ti awọn obinrin dirọmọ riyẹ-riyẹ wipe, ayafi ti nwọn ba gba owo wọn lọwọ rẹ.

Bi enia ba ri Sam ti a wiyi, enia kole ro wipe o njẹ gbese. Nitori a gbọ wipe lasiko ti Sam wa l'ẹnu iṣẹ, on ni akọwe agba ṣugbọn nipa iwa mogbọtan, mo mọtan o gun ẹṣin ni ọjọ kan, o si lọ fi ẹgba ti nwọn fi nna ẹṣin na oyinbo to jẹ ọga rẹ, nigbati aiye nyẹ ẹ tan.

Lẹhin ti nwọn daduro tan, awọn iyawo rẹ tuka, oni-redio gba Redio, onina gba ina o ta ile, o si ta ọna, o wa bẹrẹ si ringba-nraye ki ri. Ni alẹ ọjọ kan nigbati ko ri onjẹ jẹ lati owurọ wa, o lọ s'ọdọ iya ọlọka kan o ni ki o ta ọka sisi, ẹran sisi, nwọn si ta a fun. Nigbati o jẹun yo tan o pe iya ọlọka wipe on nlọ. Iya ọlọka bere wipe owo nkọ? o dahun wipe ko si owo, tabi ki mbọ ẹwu mi wa? ni iya ọlọka ba dirọ mọ, o si bẹrẹ si fa a. Ẹlomiran l'o tun wa sanwo rẹ ki o to lọ.

## Isele pa ogoji enia

ATHENS— Lọdọdun ni a ma nsaba gbọ iro iṣẹlẹ nilu yi, awọn ọjọgbọn ti wariko lasiko kan lati wadi wo kini ohun pataki ti o nfa iṣẹlẹ wa si ilu yi nigba gbogbo, nwọn sọ wipe Oke apata kan ti a npe ni Alps wa nitosi ilu na. Ati lara oke yi ni oke kan wa ti o nru eefin ti nwọn npe oruko rẹ ni Fisufiọsi (Visuvius) oke yi ni pataki ohun to nfa Iṣẹlẹ.

Lọjọ 9th oṣu July, 1956 ni a gbọ wipe iṣẹlẹ kan tun ṣẹlẹ nilu na ninu eyiti ẹmi ogoji enia rasu. A mbẹ o. Ọlọrun, l'ọ[illegible]ọ ogun ati iṣẹlẹ, Oluwa rere gba wa.

## Imale ko nje eran gifa

ONITSHA Edekoyede kan fẹ bẹ silẹ nilu yi larin awọn Imale ati ijọba. Edekoyede na bẹrẹ nigbati ijọba ilu na sọ wipe, ina Lẹnti-ki ni nwọn o ma fi pa ẹran malu fun wọn jẹ.

Awọn Imale sọ wipe, bi nwọn ba bẹrẹ si fi ina lẹntiriki pa ẹran, awọn ko ni ra a jẹ, nitoripe ko tọ suna fun Imale lati ma jẹ ẹran ti nwọn ko fi ọbẹ dumbu pẹlu orukọ Ọlọrun, haramu ni gbogbo re jẹ fun Imale.

Awọn Hausa ti o nṣowo ẹran, taku wipe, bi nwọn ko ba ye fi ina lẹntiriki pa ẹran ni Onitsha, awọn ko ni ra ẹran wa si ilu Onitsha mọ.

Awọn Hausa ti o nṣowo ẹran na tun sọ wipe ni asiko ti ijọba fẹ da ki a ma fi lẹntiriki pa ẹran yi silẹ nilẹ Hausa, awọn kọ patapata, Ijọba si gba bẹ. nwọn mu ẹnu kuro ninu ọrọ na.

## Wo Ara Re San Ki O To Wo Wa San

Ni ọjọ kan, Ọpọlọ ranṣẹ pe gbogbo awọn ara ilu Ọpọlọ, wipe on ni ọrọ lati ba wọn sọ. Akere, Oto, Kọnkọ, Iwẹ, ẹsẹ wọn pe s'ojude ọpọlọ.

Ọpọlọ bọ s'ode, o wipe, ẹnyin ọmọ iya mi ati ara ilu mi, mo ki nyin ẹ ku ọfọ, ẹ ku asẹhinde ti Akere ti ko le jẹ oye Onişin mọ ki o to ku, ṣugbọn bi o ba jẹ pe Onişegun mbẹ larin wa ni, Akere ti o ṣọ ni itan kiba ti ku rara.

Nitorina tani yio lọ kọ iṣẹ iṣegun wa lati ọdọ Dokita l'alẹ odo? gbogbo wọn pa kere. Lẹhin eyi ni Ọpọlọ dide wipe on yio lọ kọ iṣẹ na wa. Ni ọpọlo ba lọ.

Nigbati o de inu awọn ara ilu Ọpọlọ dun nwọn da aṣọ eleru lọ fi pade rẹ. L'ọjọ keji, Ọpọlọ gbe awọn alagogo s'ode wipe, bi o ba di ọjọ Eti ki ẹsẹ gbogbo ẹranko pe. Nigbati ẹsẹ pe tan, Ọpọlọ bọ s'ori apoti o wipe, mo ti lọ s'alẹ odo lọ k'oṣẹ Iṣegun, ẹnikẹni ti aisan ba nṣe, ki o wa sile iwosan on. Ajapa, rẹrin titi o fi ẹhin lelẹ o wipe iwọ yi kọ'ṣẹ iṣegun? kio kọ lọ wo itan rẹ kerewu yi san na ki o to wa wo wa san. Bẹni agbo ba fọ olukuluku si pada sile rẹ pẹlu ẹrin arin tọ s'ara.

## Irin Ajo Lo Silu Norway

(O bere 'oju ewe karun)

Ethiopia tabi iha Gusu, South Africa ni a ti wa, awon ibere won wonyi dabi efe l'oju wa, ako si je binu si nitoripe awon ko mo nkankan nipa ilu Nigeria, ayafi igbati owo eja Panla bere ni nwón to ngbo pe ilu kan nje Nigeria.

KIL'O FA SABABI LILO WA?

L'ori iwe ipe ti awon Igbimo Onișowo Norway fi ranșe pe wa, a w a enia mefa ni nwon yan lati orișirișí ile-ișe Iwe Irohin lati lo si irin ajo na. Nwon pe wa lati wa fi oju wa ri wipe eja Panla ko ni ori ti o jo ti enia, ki a le fo akoto iro buburu ti nwon npa fun wa kakiri nile yi, iro buburu ni o r o ti wipe eja Panla ni ori bi enia, nitoripe, ko si eniti o mo ibi iro na gbe ti jade wa.

Eja Panla, gegebi awon eja miran je onje to dara fun ara enia, inu omi kanna ni o wa pelu eja Herisi ati eja Sadini ati ti Salumoni. Bakanna bi ori gbogbo eja tiri beni ori eja Panla ri, aye ti o si dara fun sișe ohun jije enia ni nwon gbe nșe, ișe re ko si șoro ni sișe. Lehinti won ba pa tan, nwon a ge ori won ati ifun inu won kuro: nwon a si fo daradara, o di siso ko, ki o ba le gbe. Lehin oșu merin ti nwon ti pa eja Panla to si ti gbe daradara ni nwon yio to fi ranșe silu wa nihin.

Boya, a le ri eniti yio bere wipe kil'o șe ti nwon fi ge ori eja Panla? Gegebi ișe won nilu awon oyinbo ni ki nwon ge ori eja kuro, a w o n omo Akeko ti o ba ti lo silu Oyinbo yio ranti iru iro ti nwon npa fun awon eleja ti nwon ba fe je ori eja. Ninu ki won so wipe awon nfe fi fun Ologbo tabi aja je, ki nwon to le ri ori eja.

Ori eja ki ișe onje enia nilu Oyinbo. Bi e ba ti bi ti Salumonu tabi Herisi wo, ko si eniti ko n'e awon eja re, ko si si eniti o bere nipa ori eja Salumonu tabi ti Herisi ri. Ni ona keji, oke giga pelu Yinyin ti o nwo silu Norway ko jeki koriko 'e hu nile ilu na, ori eja wonyi ni nwon fi nșe onje fun awon eran won, bi a ba mo wipe bayi ni nkan ri, ko ni si wipe a tun m b e r e ori eja Panla mo.

Awon ojogbon alayewo ohun jije ati awon ogbogi Onișegun ti șe ayewo eja Panla, won si so wipe o dara fun jije enia, o si ntun enia l'ara șe. Emi papa si le jeri si nipa gegebi mo ti ri oye eja na si ni irin ajo mi lo s i l u Onipanla (Norway).

Ni ipari oro mi, nkole s'alai daruko die ninu awon enia pataki, awon oninurere ti o șe iranlowo gidi ti irin ajo na șe fi kun fun igbadun ati ayo nilu Norway ati ilu nla London. A w o n eniti:- Ogbeni Maeno Beardseth, Așolu ile itaja ni Oslo. Ogbeni R. F. Mathieson, Alakoso awon Olut-oja ni Norway, ati Ogbeni Carsten Hansen, Așoju owo eja ilu Norway ni ilu nla London, ati opolopo awon enia pataki ti nko le daruko tan p e l u Bale ilu Vardo (Mayor) eniti o șe a se fun iyesi alarinrin wa ti o si tun fi ohun Ami to joju pelu eja ti a fi Golu șe da wa lo'la.

Mo dupe fun gbogbo won patapata.


**Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti Ofe**

# Cooperative Supply Association Limited

## DISTRICT MEETINGS (AMENDED)

| Date | District Number | Area | Place of meeting | Time |
|---|---|---|---|---|
| Mon. " 23 | 9 | Ife Division | Ife C.P.M.U. | 10.30 a.m. |
| " " 23 | 10 | Ilesha Division | Ilesha Community Central | 3.30 p.m. |
| Tue. " 24 | 11 | Ondo Division including Okitipupa | Ondo Town Hall | 10.30 a.m. |
| " " 24 | 12 | Akure Division " Idanre | Akure Native Court Hall | 4 p.m. |
| Wed. " 25 | 13 | Owo Division | Owo Coop Hall | 10.30 a.m |
| " " 25 | 15 | Benin Division | Benin City | 4 p.m. |
| Thur. " 26 | 17 | Whole Delta | Sapele | 10,30 a.m. |
| Fri. " 27 | 16 | Afemai Division | Auchi C.P.M.U. | 10,30 a.m. |
| Sat. " 28 | 14 | Ekiti Division | Ado Ekiti Native Court Hall | 10,30 a.m. |
| Tue. " 31 | 8 | Oyo Division | Oyo Coop Weaving Society | 10,30 a.m. |
| Sat. Aug. 11 | | Final General Meeting | Mapo Hall, Ibadan | 10,30 a.m. |

### Items on the Agenda will include:

- **Reports from the Committee of Management.**
- **The Election of Delegates to the Final General Meeting**
- **Consideration of any Resolutions Submitted.**
- **Any other Business that might come before the meeting as provided in the Bye-Laws of the Association.**

ADMISSION BY MEMBERSHIP CARD ONLY.

N. B. Members should cut out and keep this list of Meetings.



## Ogun Aran (Ejo Inu)

Aradan Worm Expeller je ogun aran ... awon omode ati agbe okunrin ati obinrin. R... igo kan lati ... awon aran buburu ti o ... dann. Bi o ti ... o ... yin ... ki o ... tan. Igo ... 2/6d. Owo-Oko si je 1/-.

THE ... TRADING
... STORES,
... Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.






## ABOKI



JE AWOGBARUN to LOKIKI KA ILE ENIA DUDU.
AJEBIDAN ni fun IKO, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JEDIJEDI, etc.

KOSEFEKU ni GBOGBONSE yi je fun GBOGBO ILE nitorina RA IGO kan LONI Lodo:-

**IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,**

**Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN**

B 21, Sabongeri, ZARIA. X 5, Central Market, Box 2205,

Kumasi, Gold Coast.


ni Capital.

O ta siwa leti fenren wipe ilu Eko ni Alafin Oyo ti nwon ro l'oye wa ati pe o le lo silu Oyinbo nipa oro re na.

## Azikiwe Fe Binu F'ise Iselu Sile

(O bere loju ewe Kini)

Ohun ti a gbo wipe o fa gbogbo ijogbon na ni wipe, Ogbeni Azikiwe so pe, bo ba kan-oran ti on fi nilati ma gba ase lodo Gomina tabi lodo sekiteri agba nile oba, gegebi aye Alakoso Ijoba ti on je, okuku ya on lara lati yowo kuro ninu ise iselu patapata.

Awon ojogbon nile Ibo wariko nwon si ranse pe awon asiwaju ninu egbe N.C.N.C. ati awon Minister fun atoso oro nilu Enugu. Edekoyede ti o da eyi sile larin Gomina ati Premier ni wipe Gomina ranse si Igbimo Ila Oron wipe, oro ti awon Apakeji mu wa si igbimo, ti igbimo na si ta won kule, oro na nilati tun pada si igbimo fun atunso. Nitoripe o r o na s o k o k o nitorina ki igbimo tun oro na yewo.

Azikiwe so pe, bi oro na ti je otito to, on ti npale eru on mo diedie lo si ile on ni Onitsha.


## Irora Lakuregbe

Iwosan re lododo niyi. Bi enia ba nfe iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe, o ye ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindi rin oluwa re ko sise to o nfe iranlowo. Nitori iru amodi bayi lati se segbogi DE WITTS, y i o si fun enia ni igbadun ara

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nse iwosan Lakuregbe, danwo ki o lo ra okan ni sobu egbogi



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tan, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio deni oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi

**DE WITT'S PILLS**


## Gbanjare o, nibo ni Alafin wa?

Iyalenu lo je lati gbo wipe, odidi Baba 'Lafin' eniti ijoba mu lo si ehin odi nitori rogbodiyan ija 'gboro ti o sele nilu re ni Oyo, ni awon Alagborandun re fe ku ninu ile ti o gbe wa nilu Ilesha, lehin ti nwon ti gbade kuro lori re tan.

Ijoye Alapini Oyo, eniti o nse okan pataki ninu awon Oyomisi ti o si ... Alhadji A... Alafin Oyo ... wipe, ... wipe Ala... ba, o ya ... won ni ... Alafin ... sile ... ti ko jina ... ele ni. ... wipe lo Oyo ... k ... le se ki ...

... ti ijoba fi gbade kuro lori Alafin ..., nwon se ileri fun wipe, awon yio fun ni ibugbe ni bomiran ti yio ma gbe, sugbon awon alagborandun re, pataki ni awon egbe N.C.N.C. nwon ko simi nipa re.

**Lose to koja, mefa ninu awon Afobaje Oyo ti a npe ni Oyomisi se igbimo, nwon si yan Bello Gbadegesin, Aremo Ladigbolu, lati je Alafin titun,** were ti eyi sele ni awon awujo obinrin Oyo ba tuto s'oke ti nwon si f'oju gbaa, ti nwon si towo lo ba Ajele wipe awon ko gba ayafi ti nwon ba da Alhadji Adeyemi pada sori oye oba, Egbe awon okunrin so pe, ko nse awon Oyomisi lo ni lati yan oba bi k o s e awon yi ti o je Omoba lo to si.

Nigbati a bere si wadi ibiti a gbe wa ri nilu Eko ni ile okunrin kan ti o nra Iwo eran malu fi sowo. Nigbayi ni okan wa to bale wipe Alafin mbe

## Omo Ki Ip'omo J'aiye

Olorun Oba lo pase fun Mose wipe ko so fun awon omo Israel wipe "Iwo ko gbodo pania". Enikeni ti o ba npa ase Olorun mo ni a npe ni olotito ati olododo. Iru iwa yi ni awon Ijoba Gesi mu se ti a nse npe won ni olododo.

**Beni a ti fi ko wa ninu Bibeli wipe olododo l o ngbe orile ede leke. Enikeni ti o ba pa enia, lori re ni ao ti mu ida koja. Boya nitori iru iwa bi eyi ti awon Gesi ni, ni Olorun se ngbe won leke isoro gbogbo. Olorun ko mase jeki nwon r i spada s i buruku. Amin.**

Lenu ojo meta, awon kan jeun yio tan nigbati nwon kori oro so, nwon wipe, eni to ba pa enia, ki a mase pa oluwa re mo. Iyen nigbimo k e k e r e (House of Commons).

Nigbati oro na de igbimo awon agba, nse ni nwon yara ko pada si won lenu (House of Lords) Gomina wa atijo Sir Arthur Richard so wipe bi igbimo ba lo gba wipe, ki a mase yegi fun awon apania mo, ki ni e ti rope yio ri ni awon ile okere ti o wa labe asia Gesi. Bi awon ara ile wa lokere ba gbo, iparun mbo diedie niyen, ijagbora yio s e l e ninu eyiti ipania yio po.

Nitorina, on gba ni imoran wipe ki igbimo yi mase gba lati da awon apania si nitori omo ko npa omo jaiye ni nwon nwi.

## Elubo lo wa ra omo eran se de igba ?

JOS. Awon okunrin agbe mejo kan lo lo dako ninu ile kan, eyiti awon egbe kan ti gba ase le lori wipe dukia mbe nibe, sugbon nwon koiti setan lati bere si wa awon dukia na.

Boya ni gbati awon agbe na sakiyesi pe oro mbe ninu ile na, nwon bere si wa a, ki awon ti o ti gba ase siwaju to wa ka won mobe, ni nwon lo pe olopa.

Adajo pase pe ki awon lo fun awon agbe melejo ni egba mefa mefa nidi won.

Oruko awon agbe na ni wonyi:- Jaro Bokosi, Magini Bokosi, Mita Bokosi, Gowan Bokosi, Maji Bokosi, Gidadado Bokosi, Tom Bokosi ati Mahona Bokosi. Gbogbo won gba wipe awon jebi.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 2...